“Dajudaju Ọlọhun maa ya arákùnrin kan sọ́tọ̀ nínú ìjọ mi lójú àwọn ẹ̀dá ni ọjọ́ igbende alukiyaamọ

Lati ọdọ Abdullahi ọmọ Amru ọmọ ‘Aas- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- o sọ pe: Ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Dajudaju Ọlọhun maa ya arákùnrin kan sọ́tọ̀ nínú ìjọ mi lójú àwọn ẹ̀dá ni ọjọ́ igbende alukiyaamọ, O maa ṣí ìwé isẹ mọkandinlọgọrun-un fun un, ìwé kọ̀ọ̀kan gùn ni odiwọn ibi tí ojú bá le rína dé, lẹyin naa O maa sọ pé: Ǹjẹ́ nǹkan kan n bẹ nínú eyi ti o fẹ takò? Ǹjẹ́ àwọn malaika òǹkọ̀wé-isẹ́ ẹ̀dá ti wọn jẹ oluṣọ ṣe àbòsí rẹ bi? O maa sọ pé: Rara, Irẹ Olúwa mi, O maa sọ pé: Ǹjẹ́ o ni àwíjàre kankan bi? O maa sọ pé: Rárá, Irẹ Oluwa mi, O maa sọ pé: Ko ri bẹẹ, dájúdájú o ni isẹ rere kan ni ọdọ Wa; torí pé ko si àbòsí fun ẹ ni oni, wọn maa wa mu iwe pélébé kan jáde ti ohun ti o wa ninu rẹ jẹ: ASH’HADU AN LAA ILAAHA ILLALLOHU, WA ASH’HADU ANNA MUHAMMADAN ABDUHUU WA ROSUULUHUU, O maa sọ pé: Mu òṣùwọ̀n rẹ wá, o maa sọ pé: Irẹ Oluwa mi, iwe pélébé wo ni o wa pẹ̀lú àwọn ìwé isẹ yii? O maa sọ pé: Wọn ko nii ṣe abosi fun ọ, o sọ pe: Wọn maa gbe àwọn ìwé isẹ naa sórí abọ́ òṣùwọ̀n kan, wọn si maa fi iwe pélébé naa sórí abọ́ òṣùwọ̀n mii, ni àwọn iwe isẹ naa maa di ohun ti o fúyẹ́, ti iwe pélébé naa si maa wúwo, ko si nnkan kan ti o le wuwo ju orúkọ Ọlọhun lọ”.

[O ni alaafia] [Tirmiziy ati Ibnu Maajah ni wọn gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe dajudaju Ọlọhun maa ṣẹsa arakunrin kan ninu ijọ rẹ lójú awọn ẹda ni ọjọ igbedide, wọn maa pe e lati ṣe ìṣirò isẹ fun un, O si maa fi iwe àkọsílẹ mọkandinlọgọrun-un han an, àwọn naa ni awọn iwe awọn isẹ aburu rẹ ti o n ṣe ni aye, ati pe òró iwe àkọsílẹ kọọkan gùn ni ìwọ̀n ibi tí irina ba dé, Lẹyin naa Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ fun arakunrin naa pe: Njẹ waa tako nnkankan ninu nnkan ti wọn kọ sinu awọn iwe àkọsílẹ yii? Njẹ awọn Mọlaika mi Olùṣọ́ Olukọwe ṣe abosi rẹ? Arakunrin naa maa sọ pé: Rara Oluwa mi. Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ pé: Njẹ awijare n bẹ fun ẹ ninu nnkan ti o ti siwaju ninu awọn isẹ ni aye? Bóyá o jẹ igbagbe tabi àṣìṣe tabi aimọkan, Arakunrin naa maa sọ pé: Rara Oluwa mi, mi ko ni awijare kankan. Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ pé: Bẹẹ kọ, dajudaju daadaa kan n bẹ fun ẹ lọdọ wa, ati pe ko si abosi kan fun ẹ lónìí. O sọ pe: Yoo mu kaadi kan jade ti wọn kọ sibẹ pé: Mo n jẹrii pe ko si ẹni ti ìjọsìn tọ si ni ododo afi Allahu, mo si n jẹrii pe Muhammad ẹrusin Ọlọhun ni ati Ojisẹ Rẹ. Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ fun arakunrin yii pé: Mú òṣùwọ̀n rẹ wa. Arakunrin naa maa sọ ni ẹni ti o n ṣe eemọ pé: Irẹ Oluwa mi! Ki ni òṣùwọ̀n kaadi yii já mọ́ ni ẹgbẹ́ awọn iwe àkọsílẹ yii? Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- maa sọ pé: Abosi ko lee ṣẹlẹ si ẹ lailai. O sọ pe: Wọn yoo gbe awọn iwe àkọsílẹ naa sinu abọ́ òṣùwọ̀n kan, ati kaadi naa sinu abọ́ òṣùwọ̀n kan; bayii ni abọ́ òṣùwọ̀n ti awọn iwe àkọsílẹ wa nibẹ maa di ohun ti o fuyẹ, ti abọ́ òṣùwọ̀n ti kaadi wa ninu rẹ maa tẹsuwọn ti o maa wuwo, ni Ọlọhun ba maa fi ori jin in.